# ỌRỌ IYANJU LATI GBỌRAN SI OFIN ỌLỌRUN
## Deuteronomi 4:1-13, 32-40; 5:1-5, 23-33
### ẸKỌ 118 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "OLUWA Ọlọrun wa li awa o ma sìn, ohùn rẹ̀ li awa o si ma gbọ́" ( Joṣua 24:24).**

**A Mú Wa si Iranti**

Lori Oke Sinai ni Ọlọrun ti fi Ofin funni ti a pè ni ilana titi idajọ. O sọ fun awọn Ọmọ Israẹli pe ki wọn ranti, ni pataki, ọjọ ti Oun ba wọn sọrọ laaarin awọsanma ti o ṣú dùdù (Ẹksodu 19:9). Wọn gbọ́ bi aará ti n sán, wọn si ri bi mànàmáná ti n kọ ni akoko ti Ọlọrun fun wọn ni Ofin. Wọn si ti wariri bi iná ti sọkalẹ wá sori oke naa nigba ti Ọlọrun sọrọ (Ẹksodu 19:16-20). Wọn gbọ́ ohùn Rẹ̀ nigba ti O n ba Mose sọrọ (Ẹksodu 19:9). Ni ọjọ naa ti Ọlọrun fi ogo ati tibobi Rẹ̀ hàn wọn, awọn Ọmọ Israẹli ti ṣeleri lati ṣe "ohun gbogbo ti OLUWA wi" (Ẹksodu 19:8). Ọlọrun ti sọ fun wọn pe ki wọn má ṣe gbagbe nnkan wọnyii.

Nigba pupọ awọn eniyan n fẹ lati rán Ọlọrun leti ileri Rẹ̀. Mose ṣe bẹẹ ni akoko ti Ọlọrun sọrọ idajọ nitori awọn Ọmọ Israẹli ti yá ere ẹgbọrọ maluu lati maa sìn (Ẹksodu 32:13). Nigba miiran Ọlọrun maa n ri i pe o yẹ ki Oun rán awọn eniyan leti ileri ti wọn ti ṣe fun Oun. Nigba ti eniyan bá ba majẹmu tabi adehun rẹ̀ pẹlu Ọlọrun jẹ́, Ọlọrun ko le mu ipa ti Rẹ̀ ninu adehun naa ṣẹ mọ́. Ohun rere ni lati maa ranti ọjọ ti Ọlọrun ba wa sọrọ, ki a ma ba gbagbe awọn ileri ti a ṣe fun Un.

**Gbogbo Ofin**

Ohun ti Ọlọrun ṣe ju pe ki O rọ awọn Ọmọ Israẹli lati gbọran: O beere igbọran lọwọ wọn ni. O kilọ fun wọn lati fi iye si Ọrọ Rẹ̀ ki wọn ba le wà laaye. Wọn ni lati pa gbogbo Ofin mọ́ ti wọn ba nireti lati lọ gba Ilẹ Kenaani. Awọn Ọmọ Israẹli ni lati pa Ofin mọ́ ki wọn si mọ̀ ọ́. O ti ṣe pataki to lonii lati kọ́ Ọrọ Ọlọrun ki a ba le mọ ki ni Ofin Rẹ̀ jẹ́! Eniyan ni lati mọ Ofin Ọlọrun ki o to le pa a mọ́.

A kilọ fun awọn Ọmọ Israẹli ki wọn ma ṣe fi ohunkohun kún Ofin Ọlọrun tabi ki wọ́n yọ ohunkohun kuro ninu rẹ̀. Ni akoko kan awọn eniyan kan laaarin wọn ti fi ẹ̀sin Baali-peoru kun un. Awọn ti o jẹbi ni a pa (Numeri 25:5), ṣugbọn awọn ti o fara mọ́ Oluwa timọtimọ yè.

A n beere lọwọ awa naa lonii, lati pa gbogbo ifẹ Ọlọrun mọ́. "Gbogbo ọ̀rọ Oluwa ni funfun: on li asà fun gbogbo awọn ti o gbẹkẹ wọn le e. Iwọ máṣe fi kún ọ̀rọ rẹ̀, ki on má ba ba ọ wi, a si mu ọ li eke" (Owe 30:5, 6). "Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia" (Oniwasu 12:13). Ninu ori iwe ti o kẹyin ninu Iwe Ifihan ni awọn ọrọ ikilọ wọnyii wà: "Bi ẹnikẹni ba fi kún wọn, Ọlọrun yio fi kún awọn iyọnu ti a kọ sinu iwe yi fun u. Bi ẹnikẹni ba si mu kuro ninu ọ̀rọ iwe isọtẹlẹ yi, Ọlọrun yio si mu ipa tirẹ̀ kuro ninu iwe iye, ati kuro ninu ilu mimọ́ nì, ati kuro ninu awọn ohun ti a kọ sinu iwe yi."

**Orilẹ-ede Nla ati Ọlọgbọn**

A sọ fun awọn Ọmọ Israẹli pe ki wọn kiyesara lati maa pa gbogbo Ofin mọ́ ni kinnikinni. Nigba naa ni awọn orilẹ-ede iyoku yoo bu ọla fun wọn. Wọn o gba awọn Ọmọ Israẹli gẹgẹ bi ọlọgbọn ati ẹni oye. Wọn yoo mọ̀ pe Ọlọrun wà nitosi awọn Ọmọ Israẹli lati tọ́ wọn, lati jà fun wọn, ati lati dahùn adura wọn. Ki yoo si orilẹ-ede miiran ti yoo tobi, ti yoo lọgbọn, tabi ti yoo jẹ́ olododo bi wọn. Gbogbo nnkan wọnyii ni a ṣeleri bi wọn o ba pa Ofin Ọlọrun mọ́.

Ọpọlọpọ eniyan ni o lepa ọgbọ́n ti ayé ati agbára fun ara wọn. Awọn miiran maa n lo akoko ati owo pupọ lati jere imọ ayé ati okiki, ṣugbọn wọn a ri i pe awọn ko ti itori eyi nilaari niwaju Ọlọrun. Ọkan ninu awọn amoye ju lọ, Sọlomọni, bẹ Ọlọrun pe ki O fun oun ni ọkàn imoye ki oun ba le ṣe idajọ awọn Ọmọ Israẹli bi o ti tọ́ (1 Awọn Ọba 3:9). Sọlomọni kò beere ọgbọ́n fun anfaani oun tikara rẹ̀. O fẹ ọkàn imoye ki Ọlọrun ba le gba ọlá ati ogo nipasẹ idajọ rẹ̀. Inu Ọlọrun dùn si adura Sọlomọni. O fun Sọlomọni ni ọgbọ́n ati pẹlu rẹ̀ ọrọ̀ ati ọlá. A tun ṣeleri ẹmi gigùn pẹlu bi Sọlomọni yoo bá gbọran si aṣẹ Ọlọrun (1 Awọn Ọba 3:13, 14).

Nigba pupọ eniyan ni lati yàn tabi ki o ṣe ipinnu. Ki a má ba ṣe aṣiṣe a n beere lọwọ Ọlọrun pe ki O fun wa ni ọgbọ́n ki O si fi ohun ti a ni lati ṣe hàn wá. Bibeli sọ fun ni pe o yẹ ki eniyan beere fun ọgbọ́n bi kò ba mọ ohun ti yoo ṣe. "Bi o ba kù ọgbọn fun ẹnikẹni, ki o bère lọwọ Ọlọrun, ẹniti ifi fun gbogbo enia li ọ̀pọlọpọ, ti kì isi iba-ni-wi; a o si fifun u" (Jakọbu 1:5).

**Kikọ́ Awọn Ọmọde**

Wọn ni lati kọ́ awọn ọmọde lati mọ Ofin Ọlọrun ati lati bẹru Rẹ̀ "Ibẹ̀ru OLUWA ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n: ati imọ Ẹni-Mimọ́ li oye" (Owe 9:10). "Kiyesi i; Ẹru Oluwa, eyi li ọgbọ́n, ati lati jade kuro ninu iwa-buburu eyi li oye!" (Jobu 28:28). Ọlọrun beere lọwọ awọn ọmọde ati lọwọ awọn ọkunrin ati obirin lati gbọran si Ofin Rẹ̀. Ki i ṣe Ofin Ọlọrun nikan ni awọn baba ati iya ni lati kọ́ awọn ọmọde ṣugbọn oriṣiriṣi ọpọlọpọ nnkan ti O ti ṣe fun wọn pẹlu. A kò fi nnkan wọnyii pamọ ki a má ba gbá wọn lọ kuro ninu ọkàn wọn. Wọn sọ wọn di mimọ̀ fun awọn ọmọ wọn, ki ẹnu wọn ba le fi iyin Oluwa ati ipá Rẹ̀, ati iṣẹ-iyanu ti O ti ṣe hàn (Orin Dafidi 78:4). "Ki nwọn ki o le ma gbé ireti wọn le Ọlọrun, ki nwọn ki o má si ṣe gbagbe iṣẹ Ọlọrun, ṣugbọn ki nwọn ki o pa ofin rẹ̀ mọ́" (Orin Dafidi 78:7).

Ọlọrun n fẹ ki awọn ọmọde pẹlu awọn ọkunrin ati obirin lọjọ oni gbọran si ọrọ Rẹ̀. Bi a ba n ranti awọn ohun nla ti O n ṣe fun wa, a o maa yin In, a o si gbẹkẹle E.

**"Sa gbẹkẹle!**

**Ọna miran kò si,**

**Lati layọ n'nu Jesu**

**Ju pe k'a gbẹkẹle,"**

Inu Onigbagbọ maa n dùn o si maa n mú inu awọn ẹlomiran dùn nipa sisọ fun wọn nipa ifẹ nla Ọlọrun ti yoo yọ wọ́n kuro ninu ẹ̀ṣẹ, ti yoo si tọ́ wọn de Ọrun.

**Kò Si Ọlọrun Miiran**

Ọlọrun sọ fun awọn Ọmọ Israẹli pe ki wọn ranti bi Oun ti ṣe wọn loore to. Nitori Ọlọrun fẹran wọn (Deuteronomi 7:8), a ti gbà wọn kuro ni Egipti nipa ọwọ́ agbara Rẹ̀, nipa iṣẹ-ami ati iṣẹ-iyanu. A kò gba orilẹ-ede miiran là rí nipa iṣẹ́-ami bẹẹ. Kò si orilẹ-ede miiran ti o ti i rí titobi Rẹ̀ ati ogo Rẹ̀. Awọn Ọmọ Israẹli ti gbọ́ ohùn Rẹ̀ wọn si wà laayè. "O fi ọ̀rọ rẹ̀ hàn fun Jakọbu, aṣẹ rẹ̀ ati idajọ rẹ̀ fun Israẹli. Kò ba orile-ède kan ṣe bẽ ri; bi o si ṣe ti idajọ rẹ̀ ni, nwọn kò mọ̀ wọn" (Orin Dafidi 147:19, 20). Gbogbo nnkan wọnyii jẹ ẹri pe Ọlọrun wà pẹlu awọn Ọmọ Israẹli ati pe wọn ni agbára pẹlu Rẹ̀. Nipa nnkan wọnyii awọn Ọmọ Israẹli -- ọkunrin, obirin ati awọn ọmọde pẹlu awọn aladugbo wọn ati ọta wọn -- yoo mọ̀ pe Oluwa, Oun ni Ọlọrun kò si ẹlomiran lẹyin Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni yọ awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti?
2. Ki ni Ọlọrun fun wọn lori Oke Sinai?
3. Ki ni ṣe ti awọn Ọmọ Israẹli fi ni ọgbọ́n ju awọn orilẹ-ede iyoku?
4. Ki ni ṣe ti a paṣẹ fun wọn lati maa fi Ofin Ọlọrun kọ́ awọn ọmọde?
5. Ki ni a n beere lọwọ awọn Ọmọ Israẹli ki a ba le mu wọn wọ Ilẹ Ileri naa?
6. Ki ni ṣe ti awọn orilẹ-ede iyoku fi bẹru awọn eniyan Ọlọrun?
7. Bawo ni wọn ṣe mọ pe kò si ẹlomiran lẹyin Ọlọrun?
8. Ki ni ṣe ti a fi n gbọran si Ọlọrun ?